# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 583 SATURDAY APRIL, 18 1964 (2D)

## Obinrin Kan Ju Ọmọ Rẹ Sinu Koto !

**K**ANO:— Gbogbo Ile ẹjọ lo kunṣọṣọ ti ẹsẹ ko si gba ero nigbati awọn Ọlọpa mu ọdọmọbinrin ẹlẹyinjuẹgẹ kan, Rose Egbuna, ẹni ọdun mọkandinlogun wa si iwaju Adajọ Agba Ile ẹjọ kekere ni kutukutu owurọ ana ọjọ Ẹti ti Iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi fun ẹsua pe o gbe ọmọ rẹ ju sinu koto ni ẹhinkunle ile wọn.

Ọlọpa ti o ba obinrin na ṣ.jọ Ọgbẹni Muhammadu Makifa ṣe alaye fun ile ẹjọ pe ni ọjọ kọkanlelogbọn oṣu kẹta ọdun ti o kọja ni obinrin na bi ọmọkunrin ponkitiponkiti kan, o gbe ọmọ na sinu ile gbogbo awọn enia si wa ṣe aajo obinrin na.

Ṣugbọn nigbati o di alẹ ọjọ na ti o di o-ri-ni-kọ-mọni, ni ọdọmọbinrin na ba fi beba ati aṣọ akiṣa we ọmọ na, o si gbe sinu apamọwọ rẹ, o ṣebi ẹnipe o nlọ si ode, o si gbe ọmọ na ju sinu koto ti nwọn ti nyagbẹ si ni Ile wọn. Nigbati o di ọjọ keji ni nwọn ri ọmọ na ninu koto.

Nigbati ọdọmọbinrin ẹlẹyinjuẹgẹ na nrojọ, o ṣe alaye fun adajọ pe, on ko jẹbi ẹsun na, nitoripe ọmọ na ti ku ki on to lọ gbe sọnu, ki iṣe pe nigbati on gbe sọnu lo ku gẹgẹbi awọn Ọlọpa ti o mu on ti ṣe wi fun ile ẹjọ

Adajọ sun ọjọ gbigbọ ẹjọ na si ọjọ iwaju lori iduro ọgbọn pọnun (£30) ati onigbọwọ lori iye kanna. Bi nwọn ba ti pari ẹjọ na si ẹ o tun ma a gbọ ninu iwe Irohin wa.

## Ayọọla Sọ Pe:

# MAJA FẸ KO AWỌN OHUN ỌṢẸ WỌ'LU !



Oloye G S. Ṣowẹmimọ



Lateef Jakande

**EKO:**— Ọrọ ba ẹhin yọ ninu Ile ẹjọ giga julọ fun Orilẹ-ede Naijiria ni owurọ ana niwaju Igbimọ awọn adajọ agba marun, nigbati ọgbẹni Olu. Ayọọla, ọkan ninu awọn Agbẹjọro ti o nṣe ẹjọ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ sọ ninu Ile ẹjọ na ni owurọ ana pe, ọgbẹni Jakande ko jẹbi ẹsun iditẹ si Ijọba eyiti Adajọ agba Ọgbẹni Ṣowẹmimọ ṣe ninu Ile-ẹjọ giga ni oṣu kẹsan ọdun ti o kọja yi.

Ọgbẹni Olu. Ayọọla ṣe alaye fun Ile-ẹjọ pe "Adajọ ṣi ara rẹ lọna" nipa pe Ọgbẹni Jakande san owo fun ẹlẹri Ijọba, Ọgbẹni Henry Gleari ati Anthony Oboh

O ni owo ti Jakande san fun wọn ki iṣe owo rẹ, owo "Allied Newspaper" ni, o si wa ninu ofin pe ki o ṣe bẹ o si tun wipe ko mọ kini awọn enia na fẹ fi owo ṣe.

O tun ṣe alaye siwaju pe Oloye Anthony Enahoro lo mu awọn enia na wa si ọdọ rẹ, pe ki o san owo fun wọn, gẹgẹbi aye Oloye na Igbakeji olori ẹgbẹ Afẹnifẹre, nigbati ko si oloye Awolọwọ nile ẹniti o tun le paṣẹ ni Oloye Enahoro.

Ọgbẹni Olu. Ayọọla tun ṣe alaye fun adajọ pe, Ọgbẹni Jakande ko si ninu ipade ti awọn enia na ṣe ko si gbero lati gbe ogun dide si Apapọ Ijọba Naijiria gẹgẹbi adajọ ti ṣe wi ninu idajọ rẹ.

O tun ṣe alaye ṣiwaju ninu ọrọ rẹ wipe, ko si ọkan ninu awọn ẹlẹri Ijọba ti o sọ wipe, Jakande ba awọn ṣe ipade tabi o ba awọn lọ si Ghana.

O tun pe akiyesi adajọ si ọrọ idajọ oloye Ṣowẹmimọ nibi ti o ti sọ pe, "Ọgbẹni Jakande nfun awọn enia ni owo lati lọ si Ghana.

Ati nibiti o gbe sọ pe, "Mo gbagbọ wipe lẹhin igbati ẹgbẹ Afẹnifẹre ti kuna ninu ibo Apapọ ni nwọn ṣe da Igbimọ Ọlọgbọn ori silẹ lati ṣe eto bi nwọn o ti ṣe gba Apapọ Ijọba pẹlu ipa, ki Oloye Awolọwọ si wa di Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria."



Oloye Awolọwọ

Ọgbẹni Ayọọla sọ, bi o tilẹ jẹ wipe nitotọ ni awọn kan ṣe ipade Ọlọgbọn ori, ko si Ọgbẹni Jakande nibẹ, ko si si ẹlẹri kan ti o darukọ rẹ ti ẹjọ na fi pari.

O ni, o wa ya on lẹnu lati gbọ ninu idajọ adajọ na. Lẹhin na ni o wa pe akiyesi awọn adajọ Agba na si iwe idajọ, oju ewe kẹrindilogoji (Page 36)

Ọgbẹni Ayọọla tun ṣe alaye pe, Dokita Ọladipọ Maja ṣe alaye ninu ẹjọ rẹ niwaju adajọ pe on ni on lọ ba Jakande ti on si sọ bi on ti ṣe lọ si Ghana fun un.

O tun ṣe alaye pe Dokita Maja sọ fun Jakande pe on ti lọ si Ghana lati lọ ra awọn ohun ọṣẹ ati awọn nkan ija ogun, on si ti sọ ọrọ na fun Oloye Awolọwọ. ṣugbọn Awolọwọ lodi ṣi imọran on.

O tunṣe alaye fun Jakande pe, ti o ba jẹ wipe ọmọ Ibo kan tabi Hausa kan ni o ba wa ni iru aye ti Oloye Awolọwọ wa yi ti Ijọba fi ofin pajawiri gbe e, o ni awọn Ibo tabi Hausa ko ni kọ bi o ba jẹ pe ogun ni awọn o ba fi yanju ọran na.

O ni Dokita Maja ṣe alaye pe, kini ṣe ti nwọn fi ṣe iru eleyi si ẹniti o jẹ Olori awa ọmọ Yoruba ti a ko le ri ẹniti o lẹ yọju sita ninu gbogbo awọn ọmọ Yoruba.

O tun ṣe alaye fun Jakande pe, Ijọba ko jẹ ṣe iru nkan ti nwọn ṣe si Olori awọn Yoruba si Olori awọn Ibo tabi Hausa ki nwọn dakẹ bi awọn Yoruba ti ṣe dakẹ yi.

O tun sọ fun Jakande pe, ti awọn ko ba fẹ ti Ghana. on mọ

WO OJU EWE KẸFA

# IWA OTITỌ LARIN ILẸ WA

Aiye dorikodo bi adan to rọ dẹdẹ lori igi. Gbogbo enia aiye nku bi kiku ojo ati bi igbi omi okun ati odo lati ibi giga lọ sinu ibu. Ibẹru airijẹ airimu bo aye mọlẹ bi igba atijọ ti omi bo gbogbo ẹda alaiye mọlẹ.

## Lati Ọwọ S. O. Jaiye

Awọn oju ti o ndan fun ẹwa ati ogo di pahara bi igi asalẹ ti ko gburo omi fun ọpọ ọjọ tabi oṣu. Bakanna awọn olore ọmọ enia yọ foti kuro lati ibu gbe enia.

Fun awọn ohun to ṣelẹ ti mo nri wa mu mi bere wipe kini de sinu aiye ti gbogbo nkan fi ri bayi?

IWA OTITỌ

Ohun kẹlẹ kan wa simi niye lati fi nkan wọnyi si iranti mi pe ko si ohun ti o mu gbogbo nkan wọnyi wa ba ọmọ enia bikoṣe iwa aini otitọ ninu wọn.

Nitori otitọ ni Ọlọrun fi ṣọ aiye ro, ṣugbọn nigbati aiye ti dehin kọ awọn wọnyi daju aiye yio toro ko si ba gẹgẹ bi Ọlọrun ti fẹ ki o ri.

Idarudapọ wa ninu ode aiye wa loni nitori iwa otitọ jina si ete ati inu wa. Gbogbo wa nkun ete gẹgẹ bi awọn wundia wa ti ode oni ti nkun ete wọn pẹlu osun Oyinbo.

Iwa ifẹ, iwa ekutele jẹ ni fẹni ni o wa yi kakiri, To bẹ inu ile ko gba wa fun oru iwa buburu ti a nhu lojojumọ. Ọpọlọpọ baba lo ṣe lala lati ṣiṣẹ ati nikẹhin lati fi ogun silẹ fun ọmọ rẹ fun itọju. Ṣugbọn ki baba to ku o yan ẹniti o ro pe yio ṣe oju on lẹhin ti o nba fi aiye silẹ.

ỌMỌ ORUKAN

Gbara ti baba ku awọn to fi si itọju ohun ini rẹ fun itọju ọmọ rẹ. Njẹ awọn ti a fi si ipo igbẹkẹle yi ha ṣe bẹ bi? Nişe ni nwọn



Ọgbeni S O Jaiye

fi owo yi toju omo ti won ti nwọn si n awọn ọmọ orukan wọnyi silẹ ninu airijẹ ati airi aiye.

Ti awọn ọmọ to ni ogun di ẹniti a nti sihin si ọhun bi alai ni bugbe, bi alaini olutọju.

Iwa aiṣotọ yi ha dara bi? Kini o ro wipe ehin iwọ to hu iru iwa yi yo jẹ fun ile tirẹ lẹhin ọla?

Ọrọ Ọlọrun sọ pe bi ...paro ti nsaba lori ẹyin ti ko ye bẹni awọn to nko ọrọjọ ti ki ṣe si ipa iwa otitọ tabi ododo. Nikẹhin nwọn yo fi silẹ lagbedemeji aiye wọn, nikẹhin awọn a di alaini.

A ta ma ta ṣe ni ọrọ Ọlọrun. Nitori na iwọ ti o fi aisotọ gbe ile rẹ duro tabi, ti o ro wipe a ko ri ẹ nigbati o nhu iwa wọnyi, mọ daju pe iwa aisotọ rẹ yo wa ọ ri. Bi ata ti ri loju bẹni iwa aiṣotọ ti ri larin wa loni. Nitori gbogbo awọn ti a ro pe o ye ki nwọn mọ otitọ ati lati fi iwa yi kọ awọn enia; nwọn yapa patapata kuro ni ọna na.

ODODO OKILẸ EDE

Ọrọ Ọlọrun wipe ododo tabi otitọ ni ngbe orilẹ ede leke. Ṣugbọn diẹ ninu awọn ti a nwo bi aṣaju lo jina si awọn ọna wọnyi nitori atiri onjẹ.

Mo ro pe idi ti awọn fi hu iwa aini otitọ loni yi ni iwa aini itẹlọrun ninu ọna wọn. Ti itẹlọrun ba wa ati kuro ni ọna otitọ koni ri bẹ rara.

Ọpọ lo nsaga si awọn nkan wọnyi ti ka dara ti o ro pe ọna to tọ ni on gba, Ọna aimọ wọn rara ẹni ati amọga Iwa baje abẹlẹ ẹni.

IMULẸMOFO

Ọpọlọpọ lo nle ojiji aiye kiri eyi ti imulẹmofo ki a wipe emi ni mo wa nibẹ, Awọn wonyi ko ranti pe ko si eniti o wa nibẹ bi ko ṣe eniti Olorun fi sibẹ.

Nitori na kini iṣẹ fefe loni ona ti ko le fun ni ni imikanlẹ ati itelorun. K o yẹ ki awa enia ma m a ranti awọn gbogbo ẹ n i alaiṣotọ to ti wa ninu aiye ri ti a ṣi m ọ iberẹ a t i opin wọn pe ofo ni.

Ani aiye wa oni dorikodo fun iwa ti ko funni ni ifọkanbalẹ rara ẹniti o ngba owo gọboyi lo tile ṣe alaini isinmi rara. Awọn ti o wa labẹ ọga tun ni owo lọwọ ati igbadun ju awọn to ngba owo tabua lọ Sibẹ enia ko ronu si ipo ti a wa lode oni. J ẹ k i otitọ jọba lọkan rẹ nigba na gbogbo ọna rẹ yo tọ dada.

Odigba o.

# ITAN ILU SHOMOLU ATI IGBOBI

Lati Ọwọ IYAAFIN GRACE I. Daramọla, Eko.

Inu mi yio dun bi Olotu iwe Irohin Imọlẹ ba le gba mi ni aye ninu Irohin rẹ Oloyinmọmọ lati sọ itan kekere yi fun awọn onkawe wa ki nwọn si ri ẹkọ ti o wa ninu itan na.

Itan na lọ bayi, ọkunrin kan wa ti oruko rẹ njẹ Shomolu, Ọgbẹni Shomolu a ma a ṣiṣẹ ni Ipinlẹ Ariwa, nipa bayi, o fẹran lati maa jẹ obi gooro gẹgẹbi awọn Gambari, ṣe ti ewe ba pẹ lara ọṣẹ on na yio di ọṣẹ. Nigbamiran o tẹ Ọgbẹni Shomolu lọrun lati ma a je obi gooro ju onjẹ lọ.

Ṣe ajo ko dabi ile, nigbati o pe titi Ọgbeni Shomolu wa si Eko lati lo isinmi ọlide ti o gba ni ibi iṣẹ rẹ. Nigbati o di irọlẹ ọjọ kan o lọ si ọja Oyingbo lati wọ moto kia-kia ti o nlọ si Shomolu

Nigbati o wọ mọto na tan, laipẹ jọjọ ni ọmọ ẹkọṣẹ mọto kia kia na ba si gba owo lọwọ awọn ero inu mọto, o si mbere pe, "Shomolu Gbobi, Shomolu Gbobi, Shomolu Gbobi"

Ni asiko ti o mbere yi, Ọgbẹni Shomolu njẹ obi lenu ni asiko yi Ninu ọkan rẹ, o ro wipe ọmọ ẹkọṣẹ mọto na nsọ wipe, Shomolu gbe obi, Shomolu gbe obi. Lojiji ati lairotẹlẹ, ni ọgbẹni Shomolu ba gba ọmọ ẹkọṣẹ mọto na ni eti agbadojubolẹ ni ija ba bẹrẹ ninu mọto na ti o fi je wipe awọn ero inu mọto na nsọ pe ki Dẹrẹba mọto o duro.

Lẹsẹkẹsẹ ni dẹrẹba na ba duro lati la wọn sugbọn Ọgbeni Shomolu ko gbọ, ọmọ ẹkọṣẹ moto na ko gba ni wọn ba ko ara wọn lọ si Teṣan Olọpa Shomolu.

Nigbati nwọn de Tesan, Ọgbẹni Shomolu lo kọkọ roju, osi ṣe alaye fun awọn Ọlọpa pe, nṣe ni ọmọ ẹkọṣẹ moto na npe on ni Ole larin gbogbo enia pe on Shomolu gbe obi ti on njẹ lenu ni.

Ṣugbọn ọmọ ekọṣe na ṣe alaye pe on ko sọ pe Shomolu gbe obi ohunti on wi nipe, Shomolu 'Gbobi hoya ero ti yio sọkalẹ ni Igbobi wa ki awọn ma ba gbe oluwarẹ kọja.

Gbogbo enia ti o wa ni Tesan lo rẹrin nigbati nwọn gbọ ẹjọ na nwọn gbọ ẹjọ na nwọn si da Ọgbẹni Shomolu ni ẹbi esun na ṣugbọn nwọn ni k i o ma a lọ. Nwọn ni o ti wa si Eko pẹ ni.

Lẹhin na ni awọn Ọlọpa wa kilọ fun ọmọ onimọto na pe, ki o ma a sọ pe "Ero Shomolu o, ero Igbobi o, nipa bayi; Ọgbẹni Shomolu ko ni ro pe on ni o mba wi pe on gbe obi.

Mo dupẹ fun aye ti e gba mi Olotu, ngo tun fi itan aladun miran ranṣẹ si nyin laipẹ."

# IWE SI OLOTU

## A nfẹ Ile-Iṣẹ Ni Igbomina

Ẹjọwọ ẹgba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin lati kesi Ọlọla Ahamdu Bello alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa pe, ki Ijọba rẹ ran wa lọwọ ni Igbomina, awa na nfẹ ile-iṣẹ nla kan nibẹ, eyiti awọn Ọmọ wa ko ni mọ lọ si idalẹ mọ.

Oyẹ ki a wa Ọmọ Igbomina ni ile iṣẹ nla bi ti awọn ilu yio ku ni Ipinlẹ Ariwa, awọn Ọmọ wa na yio ni anfani bi ti awọn ilu to ku.

Mo bẹ awọn asoju wa pe ki nwọn ba wa moju to ọrọ na, nitori ki ilu wa ba le dara ni a fi yan silẹ, nwọn ko lo woran rara Kaduna, Kano ni nwọn nkọ awọn Ile-Iṣẹ si, nitorina Ile-Iṣẹ to ba yẹ Kaduna yẹ ilẹ Igbomina na pẹlu.

Ki Ọlọrun ran gbogbo ẹnyin Ọmọ Igbomina lọwọ ejẹ ki a ran ilu wa lọwọ ki a mọ wa alafia rẹ.

Ẹjẹ ki gbogbo ẹlẹgbẹjẹgbẹ pa ẹnu pọ, ki a le ni ile-iṣẹ ni ilu wa.

Emi ni
ẸNI AFẸLAMỌ
Igbomina

## Ẹnu Yoruba Ko Ṣọkan

Ẹgba mi ni aye diẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ ti njade lojojumọ lati ba awọn ọmọ Yoruba lori ipo ti Yoruba wa loni yi, Iai ṣe ana-ani ko si ẹniti ko mọ pe, ki ẹnu wa ko yẹ ilẹ Yoruba

Ki ṣe pe ki ama da ẹgbẹ silẹ kakiri ni ole mu isọkan wa afi ki ani ifẹ arawa ki asi mu wa alafia awọn ọmọnikeji wa paapa ki a fẹran ọmọnikeji wa ju ara wa lọ.

A dupẹ lọwọ Olotu iwe Irohin Imọlẹ fun awọn ọjọgbọn ti nwọn lawa loye lori iyatọtọ wa ninu Oduduwa ati Ọlọfin.

Ki a ma fo mọ ẹgbẹ kakiri ko le mu irẹpọ wa si arin Yoruba a fi ti a ba fun rawa wa irẹpọ fun ana wa, ẹ ma j ki a ma ṣi kiri.

Ẹ jẹki a finukonu ka ni ifẹ ara wa, ki a ma tu aṣiri wa fun awọn ọta wa mọ, ko si ẹniti o mọwẹ ki o ko aiye ja, Ẹ ma tu aṣiri ara nyin mọ, ko si ẹniti ko ni tirẹ lara.

Mo dupẹ pupọ Olotu fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,
S. Tẹlla,
Ogbomọsho.

## Ọtẹ Ko Dara

Ẹdakun ẹ gba mi ni aye di; ninu iwe nyin alarinrin ti njade lojojumọ lati ba awọn ọmọ ilu Ijọmu sọ atata ọrọ asiko to fun wa to yẹ ki amọ fi irẹpọ ba ara wa gbe, awọ agbalagba ki ọmọ pa owe kan pe agbalagba ki wa loja ki ori ọmọ titun ki ọ wọ, ati pe ẹniti aba ba laba ni baba.

Ẹ jẹki a pana ọtẹ to wa ni ilu Ijọmu awọn agbalagba wi nwọn ko gbọ mọ fi Ọlọrun bẹ nyin ẹ gba ọrọ si awọn alagba lẹnu. Bi aba nfẹ ki ilu Ijọmu toro ẹjẹki a gba asẹ ti awọn alagba ba pa fun wa.

Olowo ilu Ijọmu ko ni Ifọkan balẹ bẹna ni talaka ibẹ pẹlu agbẹ ko ni isinmi lori oye ti o fẹ da idakuda silẹ yi na ni.

Loju tan ẹnyin olowo ni ẹ ntapa si awọn agba eyi ko dara to rara ẹfi owo nyin gbọran si agba lẹnu ẹfi owo nyin tun ilu se

Mo fi Ọlọrun be gbogbo ọmọ Ijọmu lọmọdẹ, lagbalagba, lọkunrin ati lobinrin ki ẹ ka oro mi yi daada ki ẹkawọ ọtẹ nilẹ,

Olotu ajinde ara yio mọ jẹ.

Emi ni
J. A. ỌLANIRAN
Ijọmu

## Mo Ki Ọgbẹni Coker Ku Iṣẹ

Ọkanṣoṣo Ajanaku ni Ọgbẹni Coker jẹ nipa mimọ eto iṣẹ ọja

O ni la a kaye nipa iṣẹ ọja pupo. Ki Edumare tubọ ma ran yin lọwọ ki o si fun un ni ẹmi gigun ti o ni ore ninu

Awọn wompari mbẹ ninu oja Oko-Awo wompari ọkunrin ati wompari obinrin

Ọgbẹni kan ti a mpe ni Babaṣina ti o nṣọ (watching) ọja na nsa okun (agbara), o ngbogun ti awọn wompari na ti nwọn ti, sọ oja di ile wọn, ti nwọn nsun nibẹ, ti nwọn si nyọ awọn ara ọja lẹnu.

Alhaji Disu a ma a mu wa gba iwe itaja ni Ipa. Ki i ṣe aanu ẹni ti o ngba iwe na ni igbagbogbo. Bi ẹni na ko ba ni owo lọjọ kan nṣe ni yio taku wọnle mọ awọn lọwọ Ẹ ku iṣẹ o

Emi ni
ARA ỌJA
Eko


## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ni awọn ọjọ wọnyi, ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu yi ati ọjọ kerindinlọgbọn oṣu yi kanna (19/4/64 ati 29/4/64 eyi ni ọjọ mẹjọ mẹjọ) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgbose Str. Eko.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ.

Ki e tete de o.

LATIFU BABALỌLA
Adele Akọwe



BI O BA NI

# Iwe—Titẹ

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe Igbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ ERỌ—ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985. Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
*OWO PỌKU NI A SI NGBA*

IROHIN KO TỌ AFOJUBA
*Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo ki o si ri iyatọ*



## Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun Yi Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JẸ RI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ
ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe
"AFINIMỌNA NPA ISIN HAJI"
LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA ṢINA TABI NA OWO INAKUNA. KI O LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA
t'Oluwa jọwọ ṣe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ fun wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Olubori gbogbo ẹda patapata" Amin

"WAS SALAM"

*AKIYESI* Gbogbo Musulumi Ododo : oyẹ ki o ni na lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA
*Iye Owo 5/6, £3 fun dosini*
MANAGER
N2/99 SITTU STREET
HIbadan



## Ẹboosi Ikọ Ti Ọjọ Rẹ Ti Pẹ Lara

Awọn Egbogi Rọbirọbi ti wọn nta kakiri Igboro oko le ṣe Iwosan wọn lailai afi ki o ri oulowo Egboo ilu ko ti o ba lagbara gidigidi lati le hu Ikọ na lati ibgi "Ikọ" si ti o si ti gbilẹ Fun awọn iru Ikọ bẹ yẹ iti oti bere fun egbogi wọnyi:

**"Thmo-Ephedrin" Tabi Egbogi "Linituss"**

Fun iwosan Ikọ Asima, ikọ fere ikọ otutu igba-aiya ikọ ...fun, ikọ-gbigbẹ tabi eyiti o ma nmu ki igbẹdu, ikọ-ọna ...fun tabi pẹlu kẹlẹbẹ tabi ti o ma njẹki enia ma ha ọna-ọfun tabi aikoni le sun daradara lọsana ti enia ru nipa wahala ... ọkan ninu awọn egbogi alagbara loru-gbiyanu lati dan ... ara rẹ iwọ yio si ri iyatọ gburugidigidi wọnyi wo fun ... larin awọn si awọn oiomi ṣorokiti ti wọn nta kakiri.

O daju ni bẹ iwọ yio bẹrẹ si ri alafia, iwọ yio ma ẹun daradara wa si ma sun fọnfọn pẹlu Alafia de si ọ ni yẹn

Bere ni Ṣọbu awọn:—
Bere egbogi ajẹbina Richelet yini ṣọbu awọn
Waterloo Medicine Store
8, Plamchurch Street,Lagos
Phone: ‑2287 Nigeria, (Ọja ita Faji)

# Bi A Ti Şe Ki Irun

(LATI ỌWỌ MALLAM SALAU U-DEEN OMUPO)

Ọrọ mi toni ni nipa ni npa irun kini, Irunkiki jẹ ọranyan fun gbogbo ẹda lọkunrin ati lobinrin, quran ori 4 ẹsẹ 103 wi bayi, dajudaju irun kiki jẹ ọran yan eyiti ao fi akoko silẹ fun gbogbo awọn onigbagbọ ododo, irun ẹmarun ni a lati ki lojojumọ, kişe eyọkan gẹgẹbi o ti mọ ṣe to jẹ pe kiki irin owurọ ni o mọ nki.

A ni lati ki irun owurọ Ọsan Irọlẹ asalẹ ati ti alẹ pẹlu. Awọn irun miran tun wa lẹhin awọn ti mo ti darukọ yi. Irun Jimọ ati Irun Ọdun mejeeji ati awọn Nafila.

Irun kiki bẹrẹ lati ori aniyan pẹlu Kabara, itumo re ni gbigbe ọwọ wa mejeji soke o fihan pe a gbe Ọlọrun ga ati pe ao wipe Alhau Akabaru, ao sigbadua si Ọlọrun pẹlu Fatia ati sura lẹhin Fatia ati Sura a ni lati rukuhu-itumọ rẹ ni iteriba fun Ọlọrun pẹlu fifi ọwọ mejeji le orunkun nipa ṣe bayi, a nfi iyin ati Ogo fun Ọlọrun, lẹhin rukuhu ao naro soke pẹlu Samin llahu Liman Hamidahu si sọ pe Alhawman Rabana Walakali Hamudu ao mura ati wolẹ fun Ọlọrun.

Bi ati nfori kanlẹ, a nfi yin ati ogo fun Ọlọrun ni sujada, su uhana Rabujali Ad wabihanu-dihe, ao joko diẹ ka to ṣe sujada ti ẹlẹkeji, eleyi ni ipari Rakati kan, bayi ni a o tun si lẹ keji a ni lati joko fun sişe Ataya, lẹhin ti a ba ṣe Ataya lọkan tan Salaman Ti o ba jẹ Irun owurọ, ọsan ati Asalẹ ni, a ni lati dide soke, lẹhin Ataya a ni lati ki Irun meji si, lẹhin Irun meji a ni lati tun ṣe Ataya kato le Sala nan Salaman jẹ ami ipari irun. ti a ni lati ṣe. A foman Oluwa, Subuhanelhai 33 ati Alinamudulilhai 33 Alhahu Akibaru 33

# Kere o

Fun anifani gbogbo ẹnyin onişowo, Iwe Irohin Imọlẹ yio ṣe ipolowo awọn ọja nyin fun nyin ti ọsẹ kan gbako ki ọdun Ileya o to de ati lẹhin odun ki awọn onibara nyin le ba nyin ra ọja ọdun Ileya ti mbọ yi.

Awọn Aṣoju wa yio ma a lọ kakiri lati be re fun awọn ti o ba fẹ lati polowo ọja wọn ninu Iwe Irohin wa.

Owo pọọku ni a ngba, dan wa wo lẹkan ki o sribi ajọ rẹ yio ti ta to,Ijafara lewu o.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQARIUS (Jan. 20 - Feb. 18) Maşe fọwọ le işẹ pupọ loni bi o tilẹ jẹ wipe o nri ilọsiwaju jaburata ninu rẹ, iwọ yio ba Obinrin kan ṣepọ loni, ipade na yio si dun bi oyin.

PISCES (Feb. 19 - Mar. 20) Maşe jeki are tabi ọlẹ ba gbogbo ohun ti o ti lero lati ṣe jẹ. Işe şişe re dara loni, owo yio si tẹ ọ lọwọ. Aşalẹ oni dara lati ba Obinrin ṣere ifẹ.

ARIES (Mar. 22 - April 19) Oni dara lati fi wa owo tabi işẹ şọra ki o maşe fi ẹnu rẹ sọrọ ti tọ nigbati o ba mba obinrin kan ṣe ere ipa.

TAURUS (April 20 - May 20) Ara rẹ yio ya, inu rẹ yio si dun arisiki pupọ yio si ba ọ je, ninu awọn ti o ba ṣe pataki, Iwọ yio gbalejo airotẹlẹ, irin ajo si wa lẹsẹ re.

GEMINI (May 21 - June 21) Iwọ jẹjẹ ohun pupọ loni, ọrọ aşiri yio je itelọrun fun ọ paapa nipa owo ati arisiki awọn enia nlanla yio lowọ si ero ti o gba.

CANCER (June 22 - July 22) Bi o ba ni işẹ pataki kan lati ṣe tete yara ṣee ni ọwọ owurọ yi, arẹ yio mu ọ nipa edekoyede kan ti bẹ silẹ larin awọn ẹbi rẹ.

LEO (July 23 - Aug. 22) Ibere ọjọ oni dara fun ọ, o dara ki o fọwọ le işẹ titun kan loni, yio si dara fun ọ. Orire yio wa fun ọ loni ati lọdọ awọn obirin, Ijimi enia yio na ọ lẹhin.

VIRGO (Aug. 23 - Sept. 22) Oni dara fun ọ lati rin irinajo. Iwọ yio gbọ irohin lati ọna jinjin wa niti rere adehun ti o ba ṣe loni eio sunwọn.

LIBRA (Sept 23-Oct 23-) Işe yio pọ fun ọ loni, o si dara lati ba Obinrin şere, Maşe erepa tabi ki o wa moto tabi ki o gun keke loni, Ba gbogbo awọn ara rẹ pari ija, nitori iwọ le sọrọ kan ki o si dijangbọn.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22-)Ọrọ ija to mbẹ nibẹ ko sọro tobẹ yio pari laisi wahala, işẹ rẹ yio si ma lọ deedee.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 21-) Ilọsiwaju ni iwọ yio ma lọ lojojumọ iwọ yio si ma ba awọn enia nlanla pa nkan po Iwọ yio si ma ba awọn ẹlẹgbẹ re şişe pẹlu ifẹ.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 19) Ijafara lo da edekoyede o sẹlẹ ni owurọ yi wa. Oni dara lati gba tẹgun lọ si ode tọju alafia ara rẹ loni.


# EGBOGI JẸDIJẸDI

BERE EGBOGI



## "CYCLOVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ si nyọ ọ lenu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi Ihoidi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jedijẹdi je ọkan ninu amod i o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn a ma powo wọn fun iwosan rẹ şugbọn boya la leri mẹwa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Şugbọn awa ko ro bẹ rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana. Orişirişi Jedijedi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ. ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna ṣelu lojoujmọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Şuga tabi oniruru ohun adidun pu pọju nigbakugba. Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnşẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egbogi "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣe wa idi rẹ ki o si danwo orişi mẹta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi na pata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogid taagboro ilu Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:—

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)

DEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street Yaba — Lagos


# Ẹ ma ka Irohin Imọlẹ lojojumọ

# Adajọ Coker, Ẹ Ku Ipalẹmọ

Lati ọwọ Alhaji Y. A. Disu

Ẹyọ jẹ ere idaraya ti ilẹ Yoruba. O si ti di asa awọn ọmọ ati ara Eko. Nwọn ma a ṅṣe ere na fun sinsin-oku Ọlọla enia, ti awọn ọmọ oku na ba ni agbara rẹ lati ṣe ioawo ẹyọ na.

Amaa n a ọmọ-oloku lowo gọbọi. Oba Eko ati awon ijoye re ni nwọn ni aṣfaani owo pupọ n a ti ọmọ-oloku b a na. Ere Ẹyọ dun pupọ ju ọpọlọpọ ere abọgi-bọrisa a t i ọpọlọpọ e r e Yoruba lọ. O fẹrẹ jẹ pe, ere na si ni o dun ju gbogbo ere idaraya lọ.



Ọgbẹni G. B. O. Coker Adajọ Agba

Inu awọn ọmọ ati awọn ara ilu Eko dun pupọ, ara wọn si ya gaga nigbati o ta si eti-igbọ wọn pe, Ogunna gbongbo ti nda itọ inu igbin, Adajọ Agba G. B. O. Coker fẹ lati se Ẹyọ fun isinku Olori-Ire Olo be ba n rẹ, ati pe, o si ti nse ipalẹmọ tara-tara lati mu ifẹ rẹ se, pelu Ogo Jesu ati atilẹhin baba ati iya rẹ. Ere ẹyọ na yio si ṣe ninu oṣu yi tabi ni ibẹrẹ oṣu tombọ yi.

Ifẹ Adajọ Coker ko va wa lenu rara, Ọmọ Yoruba gidi ni adajọ agba na, o farabalẹ pupọ. O ni laa kaye pupọ. O mọ oju, o si mọ ara Afinjuẹnia ni i. /O gbọ-ede-gbẹyọ, Ọkan pataki ni baba Adajọ na jẹ ninu awọn Ẹyọ Adimu, ni igba aiye rẹ. Ọkan pata ki si ni Adajọ Agba na jẹ ninu awọn Ẹyọ Adimu lode toni, Ẹ ko ri i nkan bayi? Ẹ ko ri i pe, ọmọ-gidi, a ni ọmọ-ọkọ ni Adajọ Agba Coker? Mo bẹri sa! Mo si fila sa!! Ki Edumare tubọ ma a ran ẹ lọwọ o, ki os ṣe e pẹ si ti daada.

Mo f i anfani iwe yi da a ni imọran pelu itẹriba fun Ọlọlajulọ wa, Nnamdi Azikiwe, PRESIDENT ati fun Ọlọla wa, Ọba Adele keji ati fun Ọlọla wa, Oga awọn Adajọ-Agba Adetokunbọh Ademọla pe, ki ẹmura, ki ẹ si ṣe ẹyọ fun awọn Ọlọla wa baba ti o bi nyin lọmọ. Ẹni aye a t i anfani lati le ṣe.

Ẹ ni o w o gidi lọwọ, ẹ yaayi, ẹ s i gbajumọ ju ọgọọrọ enia lọ yika Naijiria, a ni yika Afrika lati



Alhaji Y. A. Disu

le ṣe e lasiko. Iranlọwọ Edumare ki o ma a te fun gbogbo wa o. AMIN.


BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANṢE TI NWỌN NPE NI- Eleyi yatọ patapata si awọn

**RICHALET** Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA' bi Mọn mọnọ

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe n TỌNIKI Ẹẹ ti nwọn si nt kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di o w o Iyọn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni le yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa t mọ irufẹ awọn egbogi ba awọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Iatambulu si Itali jẹ

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi alera wọnyi le se e, La kuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun. Jẹdiẹdi Akọ ba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa Egbọgi-n Amodi Apo ile itọ, ehin didun tabi baradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogi kokoro buruku t o wa i ba ẹjẹ ara rẹ patapata yio si n ẹjẹ rẹ mọ toritoni pẹ u.

Ṣa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomiran pelu.

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street (Lagos.
**Phone: 22878** Nigeria. Ọja Ita Faji)



# Gbanjo o !

Eyi ni lati kede fun gbogbo awn ONIBARA wakọ jake iado agbaiye pe ao beresi ma a ta Ọja gbanjo wa fun ti Ọdun EASTER ati ILEYA gẹgẹbi iṣe wa lọdọọdun Ohun ti o tun mu wa tete bẹrẹ gbanjo yi ni pe, iwe ti, o nti ọdọ awon ONIBARA wa wa lati:-

**Ghana, Abijan, Cotonou, Lome ati Portnovo**

Ko ni'ye pe ki a tete berẹ GBANJO na
TETE WA RA TIRẸ LONI

ỌJA GBANJO NA BERẸ LATI 28th MAR.-30th APR

| | | | |
|---|---|---|---|
| Iwe Egbogi Ajebidun 25/— | | di | 22/6d |
| Iwe Ilana Ifa, Iyanrin tite Etutu ṣiṣẹ 21/- | | di | 18/- |
| Iwe Afọṣe Iṣẹdalẹ Yoruba Psalm Iṣegun Aje 4/6d | | di | 3/- |
| Iwe Ala Nla 7/6d | | di | 5/6d |
| Iwe Ala ati Iwadi Nkan 2/6- | | di | 2/- |
| Turari Isegun Aje 10/6 | | di | 8/- |
| Certificate of Appreticeship | 7/6d | di | 5/- |
| Tailor's Measurement Book | 7/6d | di | 5/6d |
| Iwe Itan Ala 2/6d | | di | 1/- |
| Iwe Itumọ Ami Ara 4/6d | | di | 3/- |

AKIYESI:— Ẹnikẹni ti o ba ra ninu awọn ọja yi yio gba TURARI IṢẸGUN AJẸ" lọfẹ lati fi dan wa

**Shoyinka**
1-2/99 Shittu Street
Ibadan

